Kí Ni Ọlọ́run Ní Lọ́kàn Tó Fi Dá Ilẹ̀ Ayé?—Apá 3

A gbé e ka orí 3 nínú ìwé *Kí Ni Bíbélì Fi Kọ́ni Gan-an?* ó wà lórí ìkànnì www.jw.org/yo.

OHUN TÍ O FẸ́ ṢE: Ṣàyẹ̀wò ohun tó o gbà gbọ́ àti ìdí tó o fi gbà á gbọ́, wo ohun tí Bíbélì fi kọ́ni, kó o sì mọ bí wàá ṣe ṣàlàyé àwọn ohun tí o gbà gbọ́ fún àwọn ẹlòmíì.

ṢÉ ÈÈYÀN LÈ TÁN ÌṢÒRO ARÁYÉ?

1 ṢÀYẸ̀WÒ OHUN TÓ O GBÀ GBỌ́

Kí nìdí táwọn èèyàn kan lè fi dáhùn pé rárá? .....

.....

Kí nìdí táwọn kan lè fi dáhùn pé bẹẹ̀ ni? .....

.....

Kí ni **ìwọ** gbà gbọ́? .....

.....

Kí nìdí tó o fi gbà bẹẹ̀? .....

.....

www.jw.org © 2014 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania

2 WO OHUN TÍ BÍBÉLÌ FI KỌ́NI

Ìjọba èèyàn ò lè ṣe ohun tó jẹ́ pé Ìjọba Ọlọ́run nìkan ló lè ṣe.

(Wo orí 3 nínú ìwé *Bíbélì Fi Kọ́ni*, ìpínrọ̀ 13 àti 14.)

Ka Dáníẹ́lì 2:44.

Báwo ni ẹsẹ Bíbélì yìí ṣe fi hàn pé Ìjọba Ọlọ́run lágbára ju ìjọba èèyàn lọ?

.....

.....

Ka Aísáyà 9:6, 7.

Ní ìbámu pẹ̀lú àsọtẹ́lẹ̀ yìí, kí ló mú kí Ọba Ìjọba Ọlọ́run jẹ́ Alákòóso tó dáa?

.....

.....

Bí òbí kan ṣe lè yanjú ìṣòro tí ọmọ rẹ̀ ní, bẹ́ẹ̀ náà ni Jèhófà ṣe máa yanjú ìṣòro tó ń yọ aráyé lẹ́nu

www.jw.org © 2014 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania

Ìjọba Ọlọ́run máa fòpin sí gbogbo ìṣòro tó wà láyé yìí.

(Wo orí 3 nínú ìwé *Bíbélì Fi Kọ́ni*, ìpínrọ̀ 15 sí 24.)

Ka Aísáyà 33:24; 65:21-25; àti Ìṣe 24:15.

Báwo ni ayé ṣe máa rí tí Ìjọba Ọlọ́run bá ti ń ṣàkóso?

.....

.....

.....

.....

Ka Jòhánù 3:16 àti 17:3.

Kí la gbọ́dọ̀ ṣe tá a bá fẹ́ wà nínú ayé tuntun?

.....

.....

.....

.....

Kí ló wù **ẹ** jù tí o sì ń fojú sọ́nà láti ṣe nínú ayé tuntun? Kí nìdí?

.....

.....

.....

.....

www.jw.org © 2014 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania

3 ṢÀLÀYÉ ÀWỌN OHUN TÍ O GBÀ GBỌ́

TÍ ẸNÌ KAN BÁ SỌ PÉ…

Àwọn èèyàn ń ṣe oríṣiríṣi nǹkan tuntun lójoojúmọ́. Tó bá yá, ìṣòro aráyé á yanjú.

O LÈ SỌ PÉ…

Mo gbà pé àwa èèyàn ti ṣe oríṣiríṣi nǹkan tuntun. Àmọ́ Ọlọ́run máa tó ṣe nǹkan kan fún wa tí èèyàn *kankan* ò lè ṣe. Ó máa…

.....

.....

Ẹsẹ Ìwé Mímọ́ wo lo máa kà fún ẹni náà?

.....

Báwo lo ṣe máa lo ẹsẹ Ìwé Mímọ́ yẹn láti ṣàlàyé sí i nípa ohun tí ẹni yẹn sọ?

.....

TÍ ẸNÌ KAN BÁ SỌ PÉ…

Kò sírètí kankan pé ọjọ́ iwájú máa dáa; kò lè dáa jù báyìí lọ.

O LÈ SỌ PÉ…

Ohun tó ṣeé ṣe kí ọ̀pọ̀ èèyàn rò nìyẹn. Àmọ́ ohun tí mo gbà gbọ́ yàtọ̀ síyẹn, ìdí ni pé…

.....

.....

Ẹsẹ Ìwé Mímọ́ wo lo máa kà fún ẹni náà?

.....

Báwo lo ṣe máa lo ẹsẹ Ìwé Mímọ́ yẹn láti ṣàlàyé sí i nípa ohun tí ẹni yẹn sọ?

.....

www.jw.org © 2014 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania